

IMAM ALIU AMOKEỌJA

On pẹlu ogunlọgọ awọn Musulumi pataki ti owa si ile Alfa Timiyu Naibi Alawiye Oke Ẹsọ ati ile Abasi Adegboyega lati sọ ọmọ titun ti wọn bi ni oruko ni ọjọ kẹtadinlogun osu yi.

## MASE TỌRỌ NKAN TI KO MU ANFANI WA

(Lati ọwọ Mallam Ashiru Ogunsakin E. 147 Ita-Ogọ)

Olotu mo dupẹ pupọ lọwọ yin fun aye ti ẹ gba mi lati sọ itan mi yi si inu iwe rẹ oloyinmọmọ. Irawọ Obokun. itan na lọ bayi;-

Ni igba lailai ọkunrin kan pẹlu obirin kan jumọ ngbe pọ gẹgẹbi ọkọ si iyawo. sugbọn obirin yi lọ ba Orisa kan ti o wa larin ilu wọn pe ki o fun on ni ọmọ. Orisa na si wi fun u pe ko si ọmọ ti o dara ni ile, o ni awọn ti lọ si ode sugbọn awọn ọmọ buburu ni o wa nile, o si wi fun pe ki o pada wa.

Obirin yi si wi fun pe, ki o fun on ni ọkan ninu awọn ọmọ buburu na ati pe on yio gba a bẹ. Orisa na si wi fun pe ki o mu ọkan ninu awọn ọmọ buburu na ki o si ma lọ si ile rẹ.

O si ni oyun ọmọ na, o si bi ni osu kẹfa ti o bi i ni ọmọ na dide ti o si bẹrẹsi nrin. O si lọ si inu igbo, o si lọ ge igi nla kan, o si fi gbẹ ere ti giga rẹ to ẹsẹ meji abọ.

Lẹhin ti o gbẹ ere tan ni o sọ fun iya rẹ pe ki o fun on ni gbogbo awọn eran ọsan rẹ ki on ki o pa wọn si ere nla ti on gbe kalẹ yi. Iya rẹ si yọnda gbogbo awọn eran ọsin na fun u. Lẹhin ti ọmọ buburuyi pa awọn eran ọsin na si ere nla yi tan, lo tun ni on nwa nkan miran lati pa si i. Iya rẹ si da a lohun pe, ko si awọn eran ọsin ti o tun le pa a si i.

Nighana ni ọmọ yi ni iya on ni on yio tun pa si ere na, o si pa iya rẹ o si fi bọ ere nla na. Lẹhin ti o pa iya rẹ tan ni o tun npero bi on yio se tun pa baba on bọ ere na. Baba rẹ siti gbọ ere ti ọmọ yi npa, on ni si pọn ada rẹ si ile de e. Bi ọmọ buburu yi ti yọ si baba rẹ, ti o si ri ada ti o nkọ mọla lọwọ rẹ ni ba yara osalọ. Baba yi si nle e lọ titi to fi de pẹtẹlẹ ile kan ti o si subu o si di ODO. Baba yi si wọ inu ODO na, o si di OSIBATA, o si fo le oju ODO.

Lati igba yen ni OSIBATA ti leke ODO. Bi ẹba lọ si eti odo ti o dagun, enyin yio si mọ pe otitọ ni ọrọ mi. ọmọ ijọ yen lo di ODO, baba ijọ yen lo di OSIBATA ti o nfo le oju odo. Adura mi ni ki Oluwa jọwọ ki o so wa pọ gbeyagbeya ọmọ Amin Olotu me ki yin pupọ-pupọ o. Obokun yio gbe gbogbo wa o Amin

## JOMINAGI JO ANI KO JO RE JOMINAGI GBE LẸṢẸ

(Lati ọwọ A. E. Fapugbe AA 33 Oke Iro Street Ilesa.)

Olotu Irawọ Obokun, Jọwọ gba mi laye lati ba awọn ọmọ ennia sọrọ lori owe ti owa loke yi mo si ni igbagbọ pe ẹ o se eleyi fun mi lai sianiani. Ni nkan bi ọjọ melo sẹhin yi ni a gbọ lati inu redio wipe awọn ijọba afẹnifẹre se eto ninu ile asofin ni Eko wipe ki awọn ijọba mura lati rọpo oju ona reluwe ... pataki ... ko a bi karọ ẹ o jẹ ... yi ki anfani yi ba se mu ... wa fun ... Ni ọjọ kẹji yi ... ti ... ka ninu iwe irohin (Daily Times) ti ọjọ wednesday sugbọn ohun ọran na eleyi jẹ lati gbọ wipe awọn ẹgbẹ kan ... wipe ijọba ko ni owo to lati se irufẹ yi.

Kini ki a ti gbọ wipe ... iya ... mọ ohun ti ... iya ... si ma ...

Nje ba ise yi ba le se je ohun pataki tabi ayọ pataki ... kọ ni eyi yio jẹ ti Reluwe ba gba inu wa yi kọja.? E jẹki a ki yẹ ...

O ha yẹ wipe ijọba ti yio se ... yi yio gba owo ... Western region se ise yi ni.? Mo se bi gbogbo awọn ilu bi Ẹpẹ, Ogbomoso ati Ibadan ni o ni ọna reluwe ninu gbogbo ilu wọnyi tabi ijọba bere owo ti wọn fise ọna wọnyi lọwọ wọn tabi Ilesa na ko gbọdọ ri bi awọn ilu wọnyi? O di mi loju wipe ti awọn ijọba ba fi ọwọ si lati se ise reluwe yi, ti wọn ba gbe lati Ẹdẹ yio ba Ilesa kọja.

Bi awọn ijọba ba si bẹrẹ ise yi mo ni idaniloju de ninu awọn ọmọ Ijesa ti ko ni ise yio ri ise se ọpọlọpọ onisowo ni yio ma ta anfani pupọ ni yio si wọ ilu wa Sugbọn dipo eyi owo osu wọn ni wọn nja fun kio lọ siwaju si ... eleyi ha dara bi?

Nigbati awọn ẹgbẹ afẹnifẹre wa ni ijọba ti ijọba ko ti bọ si ti Akulọ ... afi oju inu wo gbogbo ohun ti wọn se. Sugbọn a tẹ ese kan bọ okun ọni nla ti a ba le mejeji bọ nkọ se ... bayi.

Nigba aiye baba wa Ogedengbe awọn ijọba Gẹsi fi reluwe lọ Ijesa wọ sugbọn Ijesa taku pe yio ... awọn ọmọ ati iyawo wọn lọ bi oniṣẹjẹpe oju dudu nigba yen ... kiise ... qlaju ... ile ... o jẹ yi ... ọrọ nkan ti awọn aakuko ... ijọba ... wọn se bayi.

Nigbati alẹ dibo ... ko si ohun ti awọn alakuko ko sọpe awọn yio da tan ki anfani ati igbega le wa fun awọn talaka ati ilu wa gẹgẹbi Yoruba.

Sugbọn kini ere wa lo ni yi.? ... wipe bi reluwe yio ba koja ni ilẹ ... yi ijọba yio jẹ gbese. kilode ti ijọba ko ... se ... ilu miran gbogbo ti wọn ... ti o ... wa jẹ pe a ... yio fi nbẹ ;

Nigbati awọn ilu miran ba ni anfani lati si reluwe ti o si dara fun ilọsiwaju ilu bẹ ohun ti yio ba fi nbẹ ti awa na ko ba yẹ fun iru anfani bẹ ki awọn ẹgbẹ NCNC da ni lohun.

E ranti nkan ti Dafidi wi ninu iwe psalmu eyiti anpe ni orin Dafidi ori 122 ẹsẹ 10 bayi wipe "Gbadura fun alafia Jerusalẹmu awọn ti ofẹ ọ yio se rere."

Emi yio ma da da yi lohun nigbakigba ti ẹba fẹ lati gbọ ọrọ lẹnu mi sugbọn emi ko fẹ ki ẹ si mi gbọ emi ko si fẹ kiẹ si iwe mi yi ka nitori agbọrọ pọ loriri ninu igboro emi kosi darukọ ẹnikankan tabi minista kan sugbọn edun ọkan mi ni eyi jẹ o. Ẹjẹ ki afi otitọ bara wa lo.

## AKIYESI PATAKI

A fẹki ẹnikẹni ti o ba fẹ ti irohin tabi ọrọ pataki sinu iwe Irawọ Obokun ni Ilesa tabi lati idaiẹ fi irufẹ iwe bẹ ọwọ si Office No. B110, Okesha Street Ilesha.

J. O. Awosan

Alabojuto Olotu

B110 Okesha Street, Ilesha

## AKIYESI

A fi eyi kede fun gbogbo awọn asoju wa ti mba wa sa iwe irohin yi pe, aso ukaseju ti ko ba san owo iwe tirẹ ki o to di ipari Osẹ kini ti yio tẹle Osu, a o da iwe rẹ duro lai si ifilọ tabi ifisun·

Nipa aṣẹ

A abojuto

E ma ka Irawo Obokun, ki e si ma p'olowo oja yin sinu re nitoripe tiyin ni.

## IRỌ NI WỌN PA MỌ KỌMOLAFẸ
)Lati ọwọ Ọgbẹni Ọmọtayọ Atiẹbi)

Pẹlu ọpọlọpọ iyanu ni mo fi irọ ni awọn Ọlọpẹ to nṣe kunde ka Akọle Olotu (Editorial) ti wọn kunde mọ Ọlọla Kọmọlafẹ npa mọ kọ ni pa Ọlọla Olu Kọmọlafẹ Ṣebi ki i ṣe Kọmọlafẹ ni ẹnikini ninu iwe ọsẹ to kọja. O ya mi lo ṣoju Ijẹṣa ni Igbimọ na, lẹnu pe Akọle Olotu na tu mọ kini ṣe ti okiki Kọmọlafẹ fi kan ọrọ ti Kọmọlafẹ sọ lọna odi to bẹ?
Eyiyi fẹrẹ le mu mi ronu si pe Ọpẹ ni ẹniti o kọ Akọle Olotu na.

Nitoripe Akintọla jẹ alatako lo fi nsọ gbogbo ọrọ to sọ ni Igbimọ nipa Reluwe Ero Ọlọla Akintọla nipe bi on ba se bi ẹniti o nja fun Ijẹṣa, Ijẹṣa yi o gba ẹgbẹ Ọlọpẹ gẹgẹ bi ẹgbẹ to fẹran wọn.

Mo fẹ ki ẹnyin ọkawe ri mọ pe

Awọn Ọlọpẹ lo ni Ipinlẹ ti Ẹkun Iwọ Orun Naijiria, kini ṣe ti Aṣoju ti Ijẹṣ to wa nibẹ lo'ruko Ọlọpẹ kọ sọpe ki Ijọba na ṣe nkan pataki fun Ilẹ Ilẹṣa bi ti awọn Ipinlẹ miran ti o jẹ ṣe kun Reluwe ni wọn lọ nṣun ni Igbimọ Akopọ.

Oniro ni wọn, nitroina ki ẹ maṣe gba wọn gbọ o.


# IWE ALAGBAFO ASO

A ṢE IWE YI FUN ANFANI AWỌN ALAGBAFỌ ATI AWỌ TI A NFỌ ASỌ FUN. NIPA IWE YI AṢỌ KO SỌNU MỌ, RA RA ARIYANJIYAN KO SI MỌ NIPA AṢỌ.

TETE RA TIRẸ KI O TO TAN. IBA DIẸ NI A ṢE.

Ẹ O RI IWE YI RA NI OFFICE:-

IJESHA PRESS LTD. B110 OKESHA
P. O. BOX 23, ILESHA.

IYE OWO RẸ:-
OKAN:- 2/-

Lati mejila si oke:- 20/- fun dosin


## KỌMỌLAFẸ ATI RELUWE AKINTỌLA
(Bẹrẹ lati oju iwe 1)

lọ si'gbo lọ si iju. Akintọla ti o sọrọ, yi mọ pe wayo ni gbogbo nkan ti on nwi.

Ẹ sa wo bi Akintọla ṣe ni ki Ijọba ṣe awọn Reluwe rẹ:-

1 Lati Enugu, lọ si Abakaliki, lọ si Ogoja, lọ si Gboko, lọ si Wukari, lọ si Yola, lọ si Biu, lọ si Maiduguri.

2 Lati Lafia lọ si Shendam, lọ si Gombe, lọ si Biu.

3 Lati Iyana Eruwa lọ si Iseyin, lọ si Ọyọ, lọ si Ogbomọṣọ, lọ si Ilọrin.

4 Lati Eko lọ si Ikorodu, lọ si Ṣagamu, lọ si Ijebu-Ode, lọ si Ondo, lọ si Ado Ekiti, lọ si Benin, lọ si Sapẹlẹ, lọ si Warri.

5 Lati Ibadan lọ si Ifẹ, lọ si Ilẹṣa, lọ si Akurẹ, lọ si Ọwọ, lọ si Ifọn, lọ si Benin, lọ si Agbor, lọ si Asaba, lọ si Onitsha, lọ si Enugu.

6 Lati Bukani lọ si Kontagora, lọ si Zaria, lọ si Birnin Kebbi, lọ si Argungu, lọ si Sokoto, lọ si Kaura-Namoda.

7 Lati Kano lọ si Azare, lọ si Potiskum, lọ si Maiduguri.

8 Lati Aba lọ si Ikot-Ekpene, lọ si Arochuku, lọ si Ikom, lọ si Mamje.

9 Lati Funtua lọ si Bakori, lọ si Malunfashi, lọ si Musawa, lọ si Katsina.

Gbogbo ọna mẹsẹsan yi, bi a ba ro wọn pọ yio jẹ igba-le-ni-ẹgbẹdogun maili (3,200 miles) bẹni owo ti a fi nṣe maili kan Reluwe ju £500,000, iyẹn jẹ ẹgbẹrun pọun lọna edegbeta.

Reluwe Akintọla ni yẹn o.

Ẹniti o kọkọ fesi si aba Akintọla yi ni Ọlọla Tafa Balewa Olotu Reluwe ati ọkọ moto. O ni on ko ri ọgbọn ninu gbogbo nkan ti Akintọla sọ silẹ yẹn, o ni ko daju pe Akintọla fi ọrọ na kan ọlọgbọn kan ki o to ma mu lọ sinu ile aṣofin. O ni Akintọla sọ nkan ti o sọ yẹn, ki a ba le sọ pe Akintọla bere Reluwe fun gbogbo ilu.

Lẹhin na ni Kọmọlafẹ dide ti o ba Akintọla wi, o ni wayo a Akintọla fi ọrọ yẹn lu, o ni ko data bẹ. Kọmọlafẹ ni nkan ti a kọkọ nṣe ti a ba ma ṣe Reluwe fun ilu kan ni pe bawo ni o yẹ ki Reluwe na lọ, ati pe kini nkan ti Reluwe na yio ma ko nibiti a ba fẹ ṣe lọ yẹn. O ni aba Akintọla yẹn yio ti Naijiria si igbese ti ọmọ-ọmọ ẹkẹrin ko ni le san tan.

Nkan ti Kọmọlafẹ wi ni yẹn ti awọn abanijẹ ati Olotu Irawọ Obokun npariwo kiri pe Kọmọlafẹ ti ka irin Reluwe ti Akintọla tẹ silẹ wa si Ilẹṣa. Awọn ope gbogbo.

Olotu Irawọ Obokun, ninu ope rẹ, sọ pe ko yẹ ki Kọmọlafẹ sọrọ rara nipa ọrọ yẹn, iyẹn nipe Olotu Irawọ Obokun fẹ ki Kọmọlafẹ fi ọkan Ijẹṣa balẹ lori nkan ti on mọ pe ko le ṣeṣe.

Akintọla fun ara rẹ sọ pe on mọ pe nkan ti on wi ko le ṣeṣe, o ni on wulẹ nfẹ ki a kọ silẹ ni. Kini itumọ kikọ silẹ ya? Lati 1927 ni Ijọba ti kọ silẹ pe awọn yio ṣe Reluwe lati Iwo lọ si ọna Benin ti yio gba ilẹ Ijẹṣa kọja.

Iyẹn wa nibẹ o, Ijọba ko ti ri owo ti yio fi ṣe. Akintọla ni ki Ijọba lọ yawo lati ṣe omiran. Elo ni Ijọba yio yọ, nigbati owo ti a fi nṣe maili Reluwe kan ju £500,000 bẹni Reluwe Akintọla si jẹ maili 3,200 lọ.

### OWO DA?

Ẹ bere lọwọ Akintọla pe lati yio rilẹ ya wa lowo na?

Nkan ti Akintọla fẹ ṣe nipe o fẹ ki Ijọba gba nkan ti ko le ṣeṣe, ki o ba le ri nkan bu wọn pe Ijọba ti o nṣe'lesi ti ko le mu ṣe ri Ijọba ti o wa lori Nigeria lode oni. Tabi pe ki Ijọba lọ da gbese, igbati owo'ri ba si wa pa soke lati san igbese yi, Akintọla pẹlu Olotu Irawọ Obokun pẹlu awọn elekun yoku ni yio kọkọ sọ pe, ṣe bi Kọmọlafe wa nbiti nwọn ti lọ fa igbese ba Naijiria yi.

Gbogbo wayo yi ni Ọlọla Balewa ati Kọmọlafẹ ri ti wọn fi ba Akintọla wi. Gbogbo awọn ara ilu iyoku ti Akintọla daruko lo mọ pe wayo ni ọrọ Akintọla yẹn, nitoriti lo ṣe ya mi lẹnu pe Olotu Irawọ Obokun ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ ninu ẹkun eko kiri ni Ilẹṣa.

Lati ibẹrẹ 1952 de opin 1954 ti Akintọla yi fi jẹ Minista ni Eko, igbati on jẹ Minisita awọn ọsise gbogbo Nigeria, ọrẹ rẹ ati ọmọ ẹgbẹ rẹ, ologbe Bode Thomas jẹ Minista Reluwe ati ọkọ moto, kiniṣe ti Akintọla ko sọ fun Ijọba igbana pe ki nwọn ṣe Reluwe lọ si Ilẹṣa, tabi Akintọla ko mọ nkan ti a npe ni Reluwe nigbana ni?

Akintọla ko fẹ ki Nigeria jẹ gbese lakoko ti on, ṣugbọn o wa fẹ ki Nigeria jẹ gbese nigbati

(Bẹrẹ ni oju iwe 8)




AWORAN IRAWỌ OBOKUN

Irawọ Obokun jade fun atunṣe Ilẹ Ijẹṣa Obokun, ko si wa fun ati da ilu si meji bikoṣepe lati papọ, ki awọn ọmọ Obokun le jumọ ja ija rere fun Orilẹ ede Obokun gẹgẹ bi itọkasi akọle ti Olotu kọ to si jade ninu iwe ọsẹ yi.



ỌGBẸNI OYINLOLA

On lo ti jẹ Kansẹlọ fun Erin Oke ninu ijọba ibilẹ, a gbọ pe on na pẹlu awọn to wọle si Erin Local Council laini alatako ninu idibo to koja laipẹ.

## ADEGBOYEGA BI ỌMỌ TITUN
(Lati Ọwọ J. OAwosan)

Ni dede agogo kan ọsan ọjọ kẹrin dinlogun osu yi ni Bọlatito Ọmọ Ogbẹni Ajibore (Okere Ọlọrunnisọmọ) tise Iyawo Ogbẹni Abasi Adegboyega alajọ Mọjimorire ti adugbo Okesha bi ọmọbirin lantitanu kan ni Ile Iwosan ti Wesley Guild Hospital ni adugbo Ijọfi.

Bi iroyin ayọ yi ti kan Ogbẹni Abasi ni awọn ọrẹ ati ojulumọ ti nlọ sile rẹ lati bayọ ayọ ọmọ titun na.

Lẹsẹkana ni ogbẹni yi ba wọle ti omko Ọti Oyinbo jade bi omi lati fi da iwọ ọmọ titun na.

Ogunlọgọ awọn enia lo si pesẹ sibẹ ajọyọ yi, ogbẹni J O Awosan tise Olotu Irawọ Obokun na wa nibi ti ati se ajọyọ na.

Ni ọjọ kẹtalelogun osu yi tise ọjọ kẹjọ ti ati bi ọmọ titun yi ni Ogbẹni Abasi Adegboyega mura lati sọ ọmọ titun na ni oruko.

Lẹsẹkanna ni ẹiẹ awọn Musulumi pataki ti pe sile ogbẹni yi lati sọ ọmọ titun na loruko, Iman Aliu Amokeoja ni enitii osiwaju adura na asi sọ ọmọ titun na ni Serifata Adegboyega. Ogunlọgọ awọn musulum pataki ti o wa sibẹ lo si se adura dada fun baba, iya, ọmọ, ati onikaluku awọn ti o wa sibẹ lati ba wọn se ajọyọ na.

Nigbati odi ọsan ni ogunlọgọ awọn ẹgbẹ Ijebuode ti Ilesa wa si ile Adegboyega fun ti ajọyọ yi,bi onikaluku ti nde ni a nfun wọn ni onjẹ, ọti ati ẹmu to dara, gbogbo wọn lo si jẹ onjẹ ajẹti.

Ajọyọ na dun pupọ tobẹ ti ogunlọgọ awọn enia fi wa nibẹ di irọlẹ ti wọn si gbadun ara wọn pẹlu ọti oyi bo.

AKỌLE OLOTU Aki Ogbẹni Abasi Adegboyega ku orire ti ọmọ titun na, Ki Ọlọrun Ko da ẹmi gbogbo wọn si ko si se ọmọ na ni ọmọ aufani. Irufẹ ire mo ti ba yi yio kari gbogbo wa o.

## ỌMODEKUNRIN KAN ATI IYA RẸ
(Lati ọwọ T. S. Falaye B 97 Okeşa Ilesa.)

Inu mi yio dun bi e le gba mi laye lati fi itan kekere siwaju nyin. Itan mi na lo i ayi.

Ni ọjọ kan ọmọdekunrin kan ji iwe wa fun iya rẹ lati ile ẹkọ. Kaka ki iya re ba wi ati ki o na bo gba ni iyan ju le ti ma jale. Nigbati ọmọde yi dagba tan o wa nji nkan tio afye lori pupọ

Ni ọjọ kan wọn wa mu o si ilecjo o wa di pe wọn ni lati pa. Ki o to ku o toro aye lati ba iya rẹ sọrọ. Bi iya re ti sunmọ bẹni o ge ni eti jẹ. Ẹnu si ya gbogbo awọn enia ti owa ni ibẹ.

Ngbana ni ọmọde na dahun pe enyin enia rere, emi wa ni ibi yi pẹlu iwa ati oro iku, sagbọn iya mi yi ni o jẹ ki nwa nibi ti o ba jepe, odi je mi ni iya nigbati emi wa ni ọmọde, ti mosi ji iwe wale emi ki ba ti wa nihin.

Itan na kọwa pe ki obi ọmọ ba ti nkan lọwọ ọmọ rẹ ki ose iwadi rẹ dada o. Ise yin yio ma lọ soke o. Ọkọ ọba koni sayin lese o amin. Nitorina enyin obi mo be yi ki ẹma foju sọ awọn ọmọ yin lọwọ lese o.

## AFIN ỌBA ỌWA ILEṢA KO BA OJU MU
(Lati ọwọ Gabriel Adegbitẹ H 45 Ilọrọ Ilesa.)

Olotu Irawọ Obokun jọwọ fun mi laye diẹ lati se iba alaye kekere yi sinu iwe rẹ ti Monday oni yi, Ọrọ nipa ti afin ọba wa yi koma ba oju mu rara. Agbalagba lo ma npa lowe pe ohun to yẹni loyeni okun ọrun ko ye adie. Mo si fi oju inu wo kise iru afin bayi lo ye ọba wa ati papa ilu Ilesa,

Ọpọlọpọ afin ibomiran ni ama nri gẹgẹbi afin Awujalẹ Alake ati ọpọlọpọ ilu ibomiran gbogbo Nitori na afin ọba wa to bojuto dada. Eyin Kansilọ wa gbogbo Ọlọla J O Fadahunsi Ọlọla C O Komolafẹ ati awọn enia pataki pataki larin ilu ki ẹ bawa tun se o. Ile kan soso ti gbogbo Ijẹsa ni fun ọba wa.

Ẹjọwọ ẹje ki a pa imọ wa pọ ki a le tun ile na kọ dada ki o le ba oju mu ati papa yio tubọ bu iyi kun Ilesa ati ọba wa na.

Itiju lo njẹ fun wa nigbati awọn alejo pataki ba nwa si afin ti won si nba gẹgẹbi o ti n yẹn. Asi tun bẹ Baba wa Ajimoko II Ọwa Ilesa lati ba wa fi ọrọ na sọkan gidigidi o.

Mo dupẹ pupọ lọwọ rẹ Olotu fun aye tiẹ gba mi,

## ATUNṢE WA NI IGBORO ILESHA
[Lati ọwọ T. S Falaye B 97 Okeşa Street Ilesa]

Si Olotu Irawọ Obokun Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye lati fi ọrọ kekere yi si iwaju nyin:- Ọrọ na niyi:- Atunṣe wa pupọ fun adugbo Okesha gẹgẹ bi oju ọna agbara ojo.

Anu ṣe mi pupọ ni ọjọ kẹrindinlogun osu yi. Nigbati ọjọ rọ gbogbo ori ọde ti mọto nrin lọ kunfun agbara ojo ni ọjọ ti mo nwi yi. Enyin Ijọba Ibilẹ, ọrọ wa fun nyin o, ọrọ na ni pe ki ẹ wa aye ki ẹ tun oju gota ti adugbo Okesha ṣe;

Bi Ilesha ti tobi to yi, ko yẹ ki igboro Ilesa le ma ri bayi. Mo bẹ nyin o, Mo fẹ ki ẹ gba ọrọ mi yẹwo. Olotu iwe irohin Ijesa, ọkọ Ọba ko ni sa nyin lẹsẹ o. ọwọ nyin yio si ma lọ so'ke o amin.

Inu mi yio dun bi Olotu Irawọ Obokun ba le gba mi laye diẹ lati bere ọrọ kekere yi lọwọ awọn onkawe Irawọ Obokun tori ọmọde ni mi ẹnyin Agba lo si npowe pe Ọmọ to ba mọwọ wẹ yio ba Agba jẹun.

Ọkan ni mo si jẹ ninu w.. ..kawe I..wọ Obeku Ẹjọwọ owo ati ẹmọ ew.. Agba? Nkan to mu bere ọrọ yi nipe ọpọlọpọ igba ni ọrọ yi ma saba dija sile nibikibi ko si ye mi di isisiyi.

Torina mo bẹ ẹnyin Agbalagba mo fẹ mọ agba ninu awọn mejeji, ẹnyin Agba lobayi ma npowe pe Agba ki wa lọja ki ori ọmọ titun wọ.

Olotu mo dupẹ fun aye diẹ to gba mi Oluwa koni jẹ ala koba o ẹhin kete lọfọ nsẹo



RELUWE ỌKỌ OJU IRIN

Iru ọna ti Reluwe bi eleyi yio ma rin ni Ọlọla Akintọla sọ la... ba pe ki wọn se iwọn ọna ti yio gun to ẹgbẹrun mẹta o le igba maili. Awọn to fesi nfi yeni pe eyi ti a tini tẹlẹ ko to ẹgbẹrun meji maili. Wọn ni kundekunde lo fi nje

## ORUN 'RE SHITU ỌMỌ IBIRONKẸ
(Lati ọwọ Prince C. A Ibironke)

Oṣe! Oṣe!! Oṣe!!! Omama ṣe kẹ, kia to ri erin o di igbo kia to ri ẹfọn o dọ dan Kia to tun ri Shitu Giwa ọmọ Ibironkẹ o di ọjọ igbende Alukiamọ, A! Ẹni rere lọ.

Iya Shitu o ma ku aṣẹhinde ọmọ rẹ, oniwa tutu bi eji Edumare Ọbaluwaye yio tu ọ ninu. Daraya Iya rere; Bi Ọlọrun ti fẹ lo ṣe iṣẹ rẹ, ku fogo fun Baba lọke, Tujuka Iya Shitu Giwa, Ọba to da igun afun laṣọ ro; Anọbi oke a da awọn ọmọ rẹ si fun ọ; Ọba a sọ wọn dagba; Aiye ti baba wọn ko jẹ Oluwa a fun awọn ọmọ jẹ; Ki Ọba ọrun feyi ṣopin ibinujẹ. O ko ni ri iku ọmọ;

Opẹ ko to ye mi, ko tete ye mi ni ọjọ Alamisi to kọja 17-3-55, Wọo ni ẹnikan gbọrun alakeji lọ, lọna Ibadan, ki lo de ki lo ti ri Wọn ni apo agbado yi lu ẹnikan nibadan, girigiri o di Ọgba oniṣegun Ade-ọyọ lọna Yemetu nile Oluyọle ni Ibadan, Oyinbo oniṣegun fọwọ mori, o bere pe tabi ko ṣẹnikan, lati tete ṣe iranlọwọ nigba apo agbado fi ma pa Ẹni rere yi ndan? Orọ to pa mọ oju Ọlọrun to, Oniṣegun yi ni adeọyọ fẹnu mu ogedẹ wipe Bi o ba ṣe enia lo mọ mọ yi apo Agbado lu Shitu Giwa ọmọ Ibironkẹ, ti Idi-Isin Iṣokun ni Ilu Obokun; Ki Ọba adakẹdajọ lọ da fun oluwa rẹ; O ni iwọ Ẹdumrre Ọba arinurode o ni eyi tia wi fogbọ lọgbọ ngbọ, o ni aruju ọmọde ba wọnyin aiye lo ma ri torun. o ni iwọ orisa o ni ọrọ 'Shitu Giwa dọwọ rẹ dandan.

Lafarọgun ni ọjọ keji ọjọ Jimọ ni Musulumi Shitu gbọrun alakeji lọ, o fọmọ silẹ kio to gbọna Ibadan lọ o faya silẹ kio to gbọrun lọ A! Shitu musulumi ko dagbere nile ko to gbọrun lọ, Orun're Shitu;

Adedolapọ Mọradeun Fowowẹ; o ma ku aṣehide aburo Ladeyinbo Salifatu Iya rẹ ọmọ to gbafẹ pẹlẹ o Adedọlọpa ọmọ Elu ijiba, Ọmọ Alugbeja maja, ọmọ opo rosọ ọmọ opo gbaja ọmọ kan dudu nile Ẹdẹ ṣe bi ọjọ ti baba rẹ joye ni Wọrọwọ lu, ọjọ na lari baba ita-akọgun nijeṣa; ọmọ Ọwa Odundun to goroye ta ra rọ ni; O dẹ lọ tu juka, kio mọkan le, Kio gba kadara rẹ, kio gbagbọ pe Ọba na ki ṣe ibi; Kio si gba daju pe bi o ba ṣe araiye lo ṣe yi Ọba Olugbala yio ṣe idajọ dandan lọjọ aijina, Ọlọrun yio da ọwọ ibi ro ni sakani gbogbo wa nilẹ Ijeṣa o HA! Shitu Giwa ọmọ Ibironkẹ Ishokun Orun're o.



ỌGBẸNI EMAN EṢỌ

On jẹ ọkan pataki ninu awọn onisowo ni ilu Ileṣa, awọn ọmọ re meji lo yege ninu idanwo aṣejade ni Ile iwe giga (Ileṣa Grammar School) eyiti irohin rẹ jade ninu iwe ọṣẹ yi.



KANSẸLỌ M I EKUNDARE

On jẹ ọkan ninu awọn ogunna gbogbo ninu Ẹgbẹ Akukọ. On na pẹlu awọn pataki ninu ẹgbẹ na to npẹlu Ọlọla Fadahunsi yi agbe-Sbe po. A rope ohun ti wọn nlọ ṣe ni lati gbe eto ijọba igbimọ kọkan kan.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. " | " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inṣi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

## IWA RUKE-RUDO. NI IBUSO MOTỌ OGBOMỌṢỌ

Lati ọwọ Ezekiel O.Arowosafe Ipetu - Ijẹsa

Jọwọ Olotu gba mi laiye lati fi ọrọ mi yi si iwaju awọn alaṣẹ Ijọba Ogbomosho papa awọn alaṣe agba Ipinlẹ Iwọ Orun Nigeria Western Regional Government. Pe ni arin ilu Ogbomoso ni ibu-sọ motọ (motor Garrage) ojẹ nkan idọti fun oju lati ri iwa ti awọn Awa-Motọ ọmọ ibilẹ ma nhu si awọn oni-motọ ajẹji.

Ti motọ kan ba jẹ ti ajẹji to ba wa ni ibusọ-motọ ko ni ri ero ko afi ti ti ọmọonilẹ ba si tan, tobẹ ti eniа ba fi aimọ wo ọkọ ajẹji awọn Aruko ati ọmọ-iṣẹ nwọn afi agbara jaju sinu ọkọ ti nwọn eyi asi ma mu rogbo-diyan ati ija pọ pupọ ni ibusọ wọn

Ti ọkọ nwọn ba ti si saju ọkọ ajeji ti nwọn ba de ileto kan lati gba ero tabi lati ja ero kalẹ nwọn ki fẹ ya, nwọn aduro si arin ọna meji ki ọkọ to mbọ lẹhin ko ma ba saju nwọn lati ko ero si ilẹ niwaju.

Awa ero lọ ero bọ sakiyesi pe ki se ilu Ọlaju bi Ogbomoṣọ ti Ajẹiẹ wa ti ọlọpa ibilẹ wa papa ni ilu Oloye wa Ọlọla Samuel Akintọla. Olori awọn alatako ni Igbimọ nla ti asofin gbogbo gbo Nigeria (Federal House of Repre.) iru iwa ibajẹ bi eleyi ko yẹ ka ma sẹlẹ Iwa jagidijagan iwa imọtaraẹninikan eyi ti ole ba alafia ilu jẹ.

Abẹ awọn alaṣẹ Ijọba wa awọn alaṣẹ ilu pe oto akoko lati fi opin si iru iwa ibajẹ bayi ni ilu ọlaju ilu ti ojẹ ibi kẹrin nititobi ni gbogbo Nigeria.

Asi tun bẹ Oga Ọlọpa ibilẹ ko ba ni moju-tọ iru iwa ibajẹ bayi ko si bani mu iru adaluru bẹ wa si iwaju idajọ. Olotu modupẹ fun aye to gba mi.



ỌGBẸNI J. O AWOSAN

On jẹ aburo fun Alfa Tiamiyu Naibi Alawiye Oke Ẹsọ. o si wa nibi ti ati se ajọyọ sisọ ọmọ titun ti Iyawo ẹgbọn rẹ bi ni ọjọ kẹtalelogun oṣu yi.

## KỌMỌLAFẸ ATI RELUWE AKINTỌLA

(Bẹrẹ lati oju iwe 4)

no ko si ni Minista mọ yi, Ọmọ Olọmọ ni a nran ni iṣẹ de toru-toru,

Akintọla rope Ijẹṣa yio dibo fun ọpẹ ni 1956 bi on ba fi ọran Reluwe lu wayo fun wọn.

Ẹ jọwọ ọga, Ijẹṣa ko gọ tọ bi ẹ ti rope nwon gọ yen o. Eniti yio fun ni ni iṣu ti a o fi gbin gbogbo oko, bi a ba de oko rẹ o yẹ ki o le sun iṣu fun ni jẹ.

Ijọba ẹgbẹ ọpẹ, ẹgbẹ Akintọla, ko le fun Ijẹṣa lowo ti o to lati tun gbogbo ọna agbegbe se Akin-tọla lọ si Eko o lọ nbere Reluwe fun gbogbo Nigeria.

Tabi Akiktọla ro pe on le tan Ijẹṣa jẹ?

Ki iṣe Ijẹṣa, a mọ ọrọ wayo yatọ si otitọ ọrọ.

Bẹni awọn kan si ma npurọ mọ Ogedengbe pe on ni ko jẹki Oyinbo ṣe Reluwe fun Ijẹṣa. Irọ funfun ni, ọna Reluwe igbana ni ko gba Ileṣa, bi o ba gba Ileṣa, Oyinbo yio ṣe nipa, bi Ogedengbe tilẹ so pe on ko fẹ.

Ni ipari ọrọ mi, mo fẹ ki awọn alabojuto Irawọ Obokun da mi lohun ibere mi pe, tani o ni Irawọ Obokun bayi, gbogbo Ijẹṣa ni tabi ẹgbẹ ọpẹ?

Nitori orin ti ẹgbẹ ọpẹ da ni-nu iwe irohin wọn ni Olotu Ira-wọ Obokun gbe ninu Irawọ Obo-kun ti March 21.

Ẹnyin abanijẹ ti a ko bajẹ, igbati ẹ ba dẹkun lati ma ba ni jẹ ni a o ba nyin jẹ.

Olotu Irawọ Obokun, ati awọn ẹegb rẹ, ẹ mura si ẹkun yin o, esan nbọ.

## E KA NIPA IJOBA YIN

Laipẹ yi, ilẹ Ijẹṣa yio di ọkan ninu awọn ipinlẹ ti o ni ijọba alajumọ-ṣepọ nipa nini igbimọ iṣejọba mejile-logun.

Wọn ni "bi ẹgungun ẹni ba njo daradara, ori ẹni a ma ya" Irawọ Obokun lero wipe yio jẹ idunnu olu-kuluku lati ma ri irohin itẹsiwaju ka nipa igbimọ-ijọba akamọ tirẹ; nitoribẹ, a ti nṣe orișiriși atunṣe ni imurasilẹ lati ma ripe irohin njade ni ọsọsẹ nipa gbogbo awọn ijọba na.

Inu wa yio dun bi ẹnyin ọkawe wa ati aṣoju wa ba fọwọsowọpọ pẹlu wa lati ripe iṣẹ na rọrun si ṣiṣe

Ọna ti ẹ fi le ran wa lọwọ nipe:-

A fẹ Aṣoju (Agent) ni ilu kọkan.

A fẹ aṣoju si ni Ileṣa.

A fẹ awọn ti yio ma fun wa ni irohin pipe.

A fẹ awọn Ọkawe kun awọn Ọkawe wa.

A fẹ ki awọn ti o mura tan lati ma ba wa ṣowo jẹ awọn ti yio ma sanwo lasiko.

Eto bi olukuluku ṣe le ma ra tabi ma ta iwe wa wa ni isalẹ iwe yi.

| | | |
|---|---|---|
| Deposit | 10 to 50 Copies -- | 10/- |
| | 50 to 100 ,, -- | 20/ |
| | 100 to 200 ,, -- | 40/- |
| Commission:- | 10 to 100 copies | 20o/o (4/- in £1) |
| | 100 to 1000 ,, | 25o/o (5/- in £1) |
| From 1000 upwards | | Special arrangement. |

All payments should be made during 1st week in the following month, latest 2nd week after which supply would be cut off without notice.

Deposit could be withdrawn after a month's notice should in case the Agent does not owe any arrears if he or she wishes to discontinue the Agency.


## BOARD OF DIRECTORS' MEETING

The meeting of the Board of Directors, Ijesha Press Ltd., takes place on Thursday the 31st of March 1955 at 5 30 pm at the Press Premises.

PUNCTUALITY IS ESSENTIAL


## Cambridge School Certificate Dec. 1954

## RESULTS

### ILESHA GRAMMAR SCHOOL

| GRADE II | | GRADE III | |
|---|---|---|---|
| Awodeyi | Olufemi | Adetolu | George |
| Eso | Ladipo | Akanle | Lawrence |
| Fowowẹ | Babatunde | Animashaun | Kayode |
| Obembe | Julius | Ẹsọ | Ọlabọde |
| Okagbue | Samuel | Farodoye | John |
| Owopetu | Obadare | Fasuyi | Timothy |
| Oyeleye | Moses | Lawale | Latunji |
| Toniola | Latifu | Ogunsanya | Emanuel |
| | | Olulode | Oludare |
| | | Popoola | Gabriel |
| | | Sule | Raji |
| | | Fayokun | Ojo |

## AKIYESI

FUN GBOGBO OMỌ ẸGBẸ ACTION GROUP ỌPẸ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ Action Group mọ pe ipade ọjọ-mẹjọ-mẹjọ ti a nṣe ni Wednesday ko yi pada nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sokan lati ma wa gbogbo ipade dede.

AKỌWE

## AKIYESI PATAKI

Ki enikẹni ti o ba fẹ kowe sinu iwe Irawọ Obokun ma kọ orukọ ti on papa njẹ pẹlu adugbo rẹ. Toripe ọpọ iwe ni anri gba laisi orukọ. Eyiti ko basi ni orukọ ako ni tẹ jade.

ALABOJUTO

Printed and Published by Ijesha Press Ltd., B110 & B149 Okesha Street, Ilesha 28 - 3 - 55